# ÀKASỌ JAKỌBU

## Gẹnẹsisi 27:41-46; 28:1-22

## ẸKỌ 23 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Emi o san ileri ifẹ mi fun OLUWA" (Orin Dafidi 116:14).**

Esau korira Jakọbu arakunrin rẹ nitori o gba ogún-ibi rẹ lọwọ rẹ. Eniyan fẹrẹ le maa kaanu fun Esau pe ohun gbogbo ni o sọnù, ṣugbọn oun ni o jẹbi. O ni lati jẹ pe ohun kan wà ninu igbesi-aye Esau ti Ọlọrun kò ni inu didun si, gẹgẹ bi O ti sọ fun Kaini, pe, "Bi iwọ ba ṣe rere, ara ki yio ha yá ọ? bi iwọ kò ba si ṣe rere, ẹ̀ṣẹ ba li ẹnu-ọ̀na" (Gẹnẹsisi 4:7). Nitori naa o ni lati jẹ pe èrè ẹṣẹ Esau ni o n jẹ. Ikorira ti o wà ninu rẹ si Jakọbu ti sọ ọ di apaniyan, nitori, gẹgẹ bi a ti kọ́ ninu ẹ̀kọ́ kan ti a ṣe ṣaaju eyi, bi ẹni kan ba korira arakunrin rẹ apaniyan ni (Matteu 5:22; 1 Johannu 3:15).

**Ẹmi Igbẹsan**

Ibinu Esau n gbina ninu ọkàn rẹ, o si pinnu lati pa arakunrin rẹ. Ṣugbọn nitori o n bọwọ fun awọn obi rẹ, o pinnu lati mú suuru titi baba rẹ yoo fi kú.

Rebeka gbọ́ ọrọ Esau o si yara ṣe ipinnu lati gba Jakọbu silẹ. O sọ fun un pe ki o pada lọ si ọdọ awọn ẹbi oun ni Harani titi ibinu Esau yoo fi lọ silẹ. Kò ni reti pe lilọ rẹ yoo pẹ́ to ọdun mọkanlelogun – ni tootọ, "ijọ́ melo kan" ni oun tilẹ wi pe yoo duro gbà. Ṣugbọn kò tun fi oju rẹ ri Jakọbu mọ́: lọna bayii oun paapaa jiya fun ipa ti o kó ninu ọna ti wọn gbà lati tan Isaaki ati Esau jẹ.

Esau ti fẹ obinrin meji ninu awọn ará Kenaani, eyi ti o jẹ ohun ibanujẹ fun Isaaki ati Rebeka. Eyi ṣí ọna silẹ fun un lati daba fun Isaaki pe ki Jakọbu lọ si Harani lati lọ yan aya fun ara rẹ laaarin awọn eniyan rẹ. Isaaki rò pe èro rere ni eyi jẹ, o si rán Jakọbu lọ pẹlu ọpọlọpọ ibukun ju ti akọkọ lọ. O ni "Ki o (eyini ni Ọlọrun) si fi ibukún Abrahamu fun ọ."

Ọlọrun ti ṣe ileri kan fun Abrahamu pe Oun yoo sọ ọ di orilẹ-ède nla, ati pe ninu irú ọmọ rẹ ni a o ti bukun fun gbogbo idile aye. Eyi jẹ asọtẹlẹ pe ni ọjọ kan Jesu yoo wá lati inu iran Abrahamu, lati bukun fun gbogbo awọn ti o ba gba A gbọ́. Aworan ti a ri nigba ti Ọlọrun pe Abrahamu jade kuro ni ilẹ Uri ti Kaldea bẹrẹ si i fara hàn, iran kẹta ni a si dé yii – Abrahamu, Isaaki, Jakọbu.

Esau ni ireti ati ri oju rere sibẹ ni oju awọn obi rẹ; nitori naa nigba ti o gbọ ti Isaaki n sọ fun Jakọbu pe ki o ma ṣe fẹ iyawo laaarin awọn ara Kenaani, o gbiyanju lati ṣe ohun ti o wù wọ́n nipa fifẹ iyawo miiran – ni akoko yii o fẹ ọmọbinrin Iṣmaẹli ẹni ti ki i ṣe ara Kenaani. Eyi kò mu aṣiṣe ti o ti ṣe tẹlẹ kuro, o si dá wa loju pe kò ri ibalẹ ọkàn pupọ nipa eyi ti o ṣe yii.

**Àlá Iyanu Kan**

Jakọbu bẹrẹ irin-ajo rẹ, eyi ni ni sisá ti o n sá lọ niwaju arakunrin rẹ. Ni opin ọjọ kin-in-ni o dubulẹ lati sùn, Ọlọrun si mu ki o lá àlá abami kan. O ri akasọ kan ti o ga de Ọrun, awọn angẹli si n goke wọn si n sọkalẹ lori rẹ. Ọlọrun wà loke rẹ O si bá Jakọbu sọrọ, O si mu ki o da a loju pe gbogbo ibukun ti Isaaki paṣẹ sori rẹ yoo ri bẹẹ ni tootọ. Ọlọrun ṣeleri ilẹ ti o wà ni ayika rẹ fun un ati pe awọn ọmọ rẹ ní iran ti o n bọ̀ yoo pọ̀ bi erupẹ ilẹ lọpọlọpọ. (Awọn wọnyii ni Ju lode oni.)

Ọlọrun tun ṣeleri fun Jakọbu pe Oun yoo pẹlu rẹ nibikibi ti o ba n lọ, ati pe Oun yoo tun mu un pada wá. Ni ọjọ ti n bọ̀ ọpọlọpọ nnkan ni yoo ṣẹlẹ ti yoo mu ki Jakọbu ronu lori awọn ileri wọnyii. Ninu awọn ẹ̀kọ́ ti a o kọ́ lai pẹ niwaju, a o kọ́ nipa awọn iṣoro ti o là kọja, ṣugbọn pe Ọlọrun kò fi i silẹ, ati pe ni ikẹyin O si mu un pada tọ baba rẹ wá.

**Angẹli Olupamọ**

Kò ha ni jẹ ohun iyanu fun wa lati ri awọn angẹli bi wọn ti n goke ti wọn si n sọkalẹ gẹgẹ bi eyi ti Jakọbu ri ninu ala rẹ? Awọn Angẹli bẹ ẹ wà, bi o tilẹ jẹ pe a kò le ri wọn. Paulu sọ bayii nipa wọn pe, "Ẹmí ti njiṣẹ ki gbogbo wọn iṣe, ti a nran lọ lati mã jọsin nitori awọn ti yio jogun igbala?" (Heberu 1:14). Ninu Orin Dafidi 34:7, a ka a pe: "Angẹli OLUWA yi awọn ti o bẹ̀ru rẹ ká, o si gbà wọn."

Nigba kan, wolii Majẹmu Laelae nì, Eliṣa wà ni ilu kan ti awọn ẹgbẹ́ ọmọ-ogun gbogun ti. Ẹru ba iranṣẹ rẹ, o si kigbe pe "Yẽ! baba mi, awa o ti ṣe?" Ṣugbọn Eliṣa wi fun un pe ki o ma ṣe bẹru nitori awọn ọmọ-ogun ti o wà pẹlu wọn pọ ju awọn ọ̀tá wọn lọ. Eliṣa si gbadura pe ki Ọlọrun ki O ṣi oju ẹmi iranṣẹ naa. Wo o bi o ti yà a

lẹnu to nigba ti o ri i ti oke naa kún fun ẹṣin ati kẹkẹ-iná eyi ti Ọlọrun rán lati daabo bo wọn! (2 Awọn Ọba 6:14-17). Awọn angẹli Ọlọrun n ṣọ́ ẹṣọ lori awọn ọmọ Rẹ̀; bi a ba si gbé ẹkẹ̀ wa le E ti a si n gbé igbesi-ayé lati wù Ú, a kò ni lati bẹru ohun ti eniyan le ṣe si wa.

Nigba ti Daniẹli wà ninu ihò kiniun, Ọlọrun rán angẹli kan lati di ẹnu awọn kiniun naa. Bibeli kò sọ fun wa pe Daniẹli ri angẹli naa, ṣugbọn o mọ̀ pe o wà nibẹ, nitori o sọ ọna ti a fi daabo bo oun fun ọba.

**Niwaju Ọlọrun**

Nigba ti Jakọbu ji ẹ̀rù ba a. Ki ni iwọ rò pe o le mu ki ẹ̀ru ba Jakọbu lẹyin ti o ri awọn angẹli daradara nì -- bi wọn ti n goke ti wọn si n sọkalẹ lati Ọrun wá si ayé ti o si tun gbọ́ bi Ọlọrun ti ṣe ileri ibukun ti o tobi ju lọ ti le fun un? Nitori ẹ̀ṣẹ wà ninu ọkàn Jakọbu ni. Oun ti sá kuro niwaju Esau nitori ẹ̀ru rẹ̀ bà a; ṣugbọn nisisiyii oun wà niwaju Ọlọrun, nitori naa ni ẹru ti o tobi ju bẹẹ lọ fi ba a.

Ọlọrun ti ṣeleri ibukun iyanu fun un ki O ba le mu majẹmu ti O ti bá Abrahamu, baba nla rẹ̀ dá ṣẹ. Ko si ohun kan ti Jakọbu ṣe lati fun un ni ẹtọ si iru awọn ibukun bẹẹ.

**Awọn Ileri Iyanu**

Ọlọrun ti ṣeleri ayọ̀ ninu ọkàn, alaafia pẹlu awọn ẹlomiran, ounjẹ ti o tó, aṣọ lati wọ̀, ati ibugbe lati gbé fun gbogbo eniyan (Filippi 4:19); ati ere ti o ga ju lọ ni opin ohun gbogbo, ayeraye ni Ọrun ti o jẹ ibi iyanu to bẹẹ ti o ga ju ohun ti a le moye rẹ lọ. Dajudaju eniyan kò ṣe ohun kan ti o le mu un yẹ fun gbogbo awọn ibukun wọnyii ṣugbọn aanu Ọlọrun ni o pese wọn silẹ, yoo si mu wọn ṣẹ ninu igbesi-ayé gbogbo awọn ti o ba gbọ́ ti Rẹ̀. Ṣugbọn ẹni ti o ba yí ọkàn rẹ̀ pada kuro lọdọ Ọlọrun kò le ri ohunkohun gbà ju ijiya lọ.

**Awọn Ẹ̀jẹ́ Jakọbu**

Jakọbu mọ̀ nisisiyii pe ẹlẹṣẹ ni oun, ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ o n fẹ lati ṣe ohun kan nipa rẹ. O ji ni kutukutu owurọ, o fi ọwọ̀n kan lẹlẹ, o si ta ororo si ori rẹ̀ ni imurasilẹ fun ijọsin rẹ. O ni, “OLUWA mbẹ nihinyi nitõtọ; emi kò si mọ̀.” Wo iru anfaani ti o jẹ ti wa lati maa jọsin nibi ti Ọlọrun wa.

Jakọbu jẹ́ ẹjẹ kan ni owurọ ọjọ yii eyi ti o yọri si iyipada ninu ọkàn rẹ̀. Bi o tilẹ jẹ pe nigba kan ri o ti gba gbogbo nnkan mọra fun ara rẹ, lai ro ti ẹlomiran, o n fẹ nisisiyii pe ki Ọlọrun ṣe amọna oun. Gbogbo nnkan ti o beere ṣa ni ounjẹ ti o to, aṣọ ti o tó lati wọ̀, ati pe ki oun le pada bọ̀ ni alaafia si ile baba oun. Kiki igba ti eniyan ba di atunbi, nigba ti a ba gba a là kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ nipa Ẹjẹ Jesu nikan ni iru iyipada ọkàn bayii le de. Nipa jijọwọ ayé rẹ̀ fun Ọlọrun o fi ara rẹ̀ si ipo lati ri awọn ibukun ti a ti ṣeleri rẹ̀ gbà.

Jakọbu tun ṣe ileri lati maa san idamẹwaa lati igba yii lọ. O pinnu lati fi idamẹwaa ohun-ini rẹ̀ fun Oluwa. A ṣakiyesi pe bayii ni o wí, “Ninu ohun gbogbo ti iwọ o fi fun mi.” Oun ki yoo tikara rẹ wá nnkan fun ara rẹ mọ́, ṣugbọn o gbẹkẹ le aanu Ọlọrun lati pese fun aini rẹ̀ ni ọjọ ti n bọ̀. A o kọ́ ẹ̀kọ́ pe Ọlọrun bukun ifi-ara-rubọ yii O si san án lọpọlọpọ fun Jakọbu nipa ti ara ati nipa ti ẹmi pẹlu.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Esau ṣe mọ̀ ọn lara nigba ti o gbọ́ pe Baba oun ti fi ibukun naa fun Jakọbu?
2. Njẹ ibukun ti a fi fun Jakọbu ha n tẹle e lẹyin?
3. Ki ni Jakọbu fi ṣe irọri?
4. Ki ni ẹ̀jẹ́ Jakọbu?
5. Njẹ o yẹ ki a maa san idamẹwaa lọjọ oni?